# ABRAHAMU ATI LỌTI

### Gẹnẹsisi 13:1-18; 18:1-8, 16-19

### ẸKỌ 9 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀; gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kún u fun nyin" (Matteu 6:33).**

**Ọlà**

Abrahamu ni ẹran-ọsin pupọ. Ọlọrun ti mu ki Abrahamu là nitori o gbọran. Abrahamu ti jẹ́ ipè Ọlọrun, o ti fi ilu ibilẹ rẹ̀ silẹ, o si ti jade lọ si ibi ti Ọlọrun dari rẹ̀ si, Lọti ọmọ arakunrin rẹ̀ ba a lọ, oun naa pẹlu si ni ẹran-ọsin pupọ. Ẹbá awọn oke kún fun agbo-ẹran ati ọwọ-ẹran, ati agọ wọn. Wọn pọ to bẹẹ ti o fẹrẹ má si àye to fun gbogbo wọn lati maa gbé pọ̀. Awọn darandaran naa ṣe gbolohun asọ̀. Olukuluku n fẹ koriko ti o dara ju lọ ati pápá ti o sunmọ tosi ju fun ẹran oluwa rẹ̀. Ija a maa mu ọkàn eniyan bajẹ, ko si tẹ́ Ọlọrun lọrun. Ẹni kan ko le dá jà; o gba ki eniyan to meji ki ija to le wà.

**Kò Gbọdọ si Asọ̀**

Lẹsẹkẹsẹ ti Abrahamu gbọ́ nipa gbolohun asọ̀ ti ó wà laaarin awọn darandaran ti rẹ̀ ati ti Lọti, o fi opin si i. Bibeli wi pe, "Iranṣẹ Oluwa kò si gbọdọ jà; bikoṣe ki o jẹ ẹni pẹlẹ si enia gbogbo" (2 Timoteu 2:24). O dabi ẹni pe awọn ọmọde miiran fẹran wahala wọn a si maa firàn si ẹlomrian nigba gbogbo. Wọn ko ni Jesu ninu ọkàn wọn. A ka a pe, "Ẹniti o fẹ ija, o fẹ ẹ̀ṣẹ" (Owe 17:19). Awọn ọmọde ni lati ranti ẹkọ Kristi ti o wi pe, "Alabukún-fun li awọn onilaja: nitori ọmọ Ọlọrun ni a ó ma pè wọn" (Matteu 5:9). A ka ninu Iwe Owe pe igberaga ati irira ni n fa ija (Owe 10:12; 13:10), ati pe "Ọlá ni fun enia lati ṣiwọ kuro ninu ìja" (Owe 20:3).

Ninu awọn akọsilẹ Paulu a kọ́ ni pe ki a "máṣe fi ìja tabi ogo asan ṣe ohunkohun: ṣugbọn ni irẹlẹ ọkàn ki olukuluku ro awọn ẹlomiran si ẹniti o san ju on tikararẹ̀ lọ" (Filippi 2:3). Abrahamu ko ri akọsilẹ Paulu kà ṣugbọn o ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ, o si ṣe gẹgẹ bi Paulu ti wi pe Onigbagbọ ni lati ṣe. Ni aimọ ti ara rẹ̀ nikan, Abrahamu fun ọmọ arakunrin rẹ̀ ni àye lati kọkọ yan pápá oko. Nitori àye ko si fun gbogbo ẹran-ọsin, ohun ti o ṣanfaani ju lọ ni lati pinya ki wọn ba le ni irẹpọ ati lati mu ki iṣọkan wà laaarin awọn darandaran ati laaarin awọn ẹbi wọn. Nigba miiran o gba pe ki ẹni kan juwọ silẹ fun ẹni keji lati le pa iṣọkan mọ́. Abrahamu rẹ ara rẹ̀ silẹ. Oun i ba ti lo ẹtọ rẹ̀, pe oun ni o ni lati kọ́ yàn nitori oun jẹ́ ẹgbọn, pe Ọlọrun ti ṣe ileri ilẹ naa fun oun, ati pe oun ni Ọlọrun ti pe sinu ilẹ titun yii ati pe Lọti kan bá oun wá ni. Abrahamu ko sọ nnkan kan ninu iwọnyi. O ṣetan lati gba ipo keji, bi yoo ba gbà bẹẹ, lati mu ki alaafia wà laaarin ẹbi. O wi pe "Máṣe jẹ ki gbolohùn asọ̀ ki o wà … nitori pe ará li awa iṣe." O fi ọkàn ilawọ́ sọ fun Lọti lati kọ́ yàn. Satani a maa gbiyanju lati mu ki awọn eniyan jẹ́ amọ-ti-ara-ẹni-nikan ati ọkanjuwa. Jesu a maa ràn wọn lọwọ ki wọn ki wọn le jẹ alaimọ-ti-ara-wọn nikan ati onifẹ nigba ti O ba gba ọkàn wọn là ti O ba si fun wọn ni ọkàn titun. Wọn ni lati maa gbadura ki Satani ma ba le dá ẹ̀ṣẹ wọnyii pada sinu igbesi-ayé wọn. Nigba ti ẹni kan ba wá lati ba ọ ṣire, Satani le dán ọ wò. Ta ni yoo lo awọn iṣire rẹ, paapaa awọn ti o fẹran jù? Ta ni yoo kọ́ mú orombo tabi ẹran, paapaa bi ọ̀kan ba tobi ju ekeji lọ?

**Yiyan ti Ko Dara**

Ki Lọti to yàn, o wò yika lati ri ilẹ ti o dara ju lọ. O ri pẹtẹlẹ Jọrdani pe omi pọ nibẹ ati pe o ri "bi ọgbà OLUWA." Lọti yan gbogbo pẹtẹlẹ ti o ni omi pupọ naa fun ara rẹ̀ ati ẹran-ọsin rẹ̀. Abrahamu ati Lọti pinya. Lọti rin lọ si iha ila-oorun sinu pẹtẹlẹ Jọrdani ti o ni omi pupọ ti o si kún fun koriko o si pa agọ rẹ̀ titi de Sodomu ilu buburu gidigidi.

**Erè ti Ara**

Lọti ko gbadura ki o si beere lọwọ Ọlọrun ki ni yoo ṣanfaani jù fun oun. O gbagbe nipa arakunrin baba rẹ̀. Kiki nnkan ti oju Lọti ri ni pẹtẹlẹ ti o kun fun omi nibi ti koriko gbé pọ̀ si fun ẹran-ọsin rẹ̀. Ko wo ohun ti Ọrun. Lọti dabi ẹni ti o wà fun èrè ti ara, ti o si sọ iran ohun ti o dara ju ti i ṣe ti ẹmi nù.

Wò bi i ba ti dara pupọ to fun Lọti bi o ba ṣe pe o ti bọwọ fun arakunrin baba rẹ̀ ki o si yẹ ẹ si! Ọrọ Ọlọrun kọ́ ni lati maa ni ẹmi irẹlẹ, lati ni ero fun ẹlomiran ati lati bọwọ fun àgbà. Bi o ba ṣe pe Lọti kò jẹ alaimọ-ti-ara-rẹ̀-nikan gẹgẹ bi arakunrin baba rẹ̀, oun i ba ti wi pe, "Abrahamu, arakunrin baba mi, iwọ ni yoo

kọkọ yàn.  O jù mi lọ, o si yẹ ki o kọkọ yàn."  Ọlọrun i ba ti bukun fun un, oun naa i ba si ri koriko fun ẹran-ọsin rẹ̀ pẹlu.

Awọn ọmọ miiran n fi ọpọlọpọ akoko ṣire to bẹẹ ti wọn fi ni iba akoko diẹ lati fi kọ́ ẹkọ Ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi tabi lati fi kọ́ akọsori.  Awọn ọmọ miiran ti ko ni igbala n ná owó wọn lati maa fi wo aworan ti n rin ati awọn iwe itan ati arofọ ti n pa ni lẹrin lasan to bẹẹ ti wọn ko le ni owo pupọ lati ná lori ẹkọ orin kikọ eyi ti i ba fi kun talẹnti wọn ti wọn i ba le lò fun Oluwa ni ọjọ iwaju.  Awọn ọmọde wọnni n fẹ nnkan ayé nikan, wọn ko si ṣafẹri ibukun Ọrun.  Nnkan ayé ki i duro pẹ ki i si tẹ ni lọrun, ṣugbọn nnkan ti ẹmi maa n mu igbadun tootọ wa nihin yii ati ere ti Ọrun.  Niwọn igba ti Lọti wà pẹlu Abrahamu, o ṣe rere.  Ki ni yoo ṣẹlẹ nigba ti Lọti fi i silẹ?  Lọti yoo ha ni itara si iṣẹ rẹ̀ nigba ti oun ko si ni tosi akoso Abrahamu mọ́?  Lọti yoo ha ṣe rere nigba ti o kun fun imọ-ti-ara-ẹni to bẹẹ?  A o ha dán an wò lati lọ sinu ilu buburu Sodomu?

**Ibukún Kikún**

Eniyan le rò pe Abrahamu ko huwa ọlọgbọn nipa fifun Lọti ni anfaani lati kọ́ yàn.  Ṣugbọn ki i ṣe ibukun ti ko nilaari ni Abrahamu ri gbà.  Ninu ọkàn rẹ̀, Abrahamu ni alaafia eyi ti n jade lati inu ṣiṣe ohun ti o tọ́.  Ninu igbesi-ayé rẹ̀ ni ibukun Oluwa wà nitori o n fẹ iṣọkan dipo ijà.  Ohun ti Abrahamu yàn ni lati ṣe ohun ti o tọ́, ati lati fi ohun ti ẹmi ṣaaju ohun ti ayé.  Abrahamu yan Ọlọrun.  Ọlọrun bukun fun Abrahamu. Ni tootọ, Ọlọrun fun Abrahamu ni ibukun ti ara pẹlu ti ẹmi.

Ọlọrun ba Abrahamu sọrọ.  O sọ fun un pe ki o wo iha ila-oorun bi o ti le riran jinna to, ki o wo iha iwọ oorun bi o ti le riran jinna to, ki o wo iha ariwa bi o ti le riran jinna to, ati si iha guusu bi o ti le riran jinna to.  Ọlọrun fun Abrahamu ni gbogbo ilẹ ti o le ri.  Ọlọrun sọ majẹmu Rẹ̀ lati bukun fun Abrahamu di ọ̀tun.  Abrahamu naa si tẹ́ pẹpẹ o si sin Oluwa.  Nigba gbogbo ni Abrahamu n tẹ́ pẹpẹ lati sin Ọlorun.  Kò tilẹ si ibi kankan ninu Bibeli ti a gbé kà pe Lọti fi igba kan tẹ́ pẹpẹ fun Oluwa.  Ẹ má ṣe jẹ ki a ṣe ainaani ijọsin Ọlọrun.

Ni ọtọọtọ akoko ni Ọlọrun bẹ Abrahamu wò.  "A si pè e li ọ̀rẹ́ Ọlọrun" (Jakọbu 2:23).  Nigba kan Ọlọrun wi fun un pe "Ma rìn niwaju mi, ki iwọ ki o si pé."  Ọlọrun fi orukọ titun fun un.  Ṣaaju igba yii a ti mọ ọn ni "Abramu," ṣugbọn lati igba yii lọ a n pe e ni "Abrahamu."

Ọlọrun sọ ni ti Abrahamu pe: "Nitoriti mo mọ̀ ọ pe, on o fi aṣẹ fun awọn ọmọ rẹ̀ ati fun awọn ara ile rẹ̀ lẹhin rẹ̀, ki nwọn ki o ma pa ọ̀na OLUWA mọ́ lati ṣe ododo ati idajọ."  Ki ni Ọlọrun le wi nipa ti rẹ?

**Ohun Ti Iwọ Yàn**

Inu Ọlọrun maa n dùn ti awọn eniyan ba fi ifẹ wọn sori nnkan ti oke, ti ki i ṣe lori nnkan ti ayé nitori nibi ti iṣura wọn ba gbé wà, nibẹ ni ọkàn wọn yoo wà pẹlu.  Jesu ṣe ileri pe: "Ṣugbọn ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀; gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kún u fun nyin" (Matteu 6:33).  Ki ni iwọ fẹran jù, nnkan ti ayé tabi nnkan ti ẹmi?  Ki ni ohun ti o yàn – lati tẹle Ọlọrun tabi lati maa lepa nnkan ti ayé?

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti Ọlọrun sọ Abrahamu di ọlọla?

2 Ki ni ṣe ti Lọti ati Abrahamu fi pinya?

3 Ta ni kọkọ yàn?

4 Ki ni ṣe ti Abrahamu ko fẹ gbolohun asọ̀ laaarin awọn darandaran?

5 Ewo ni Lọti yàn?

6 Ki ni ṣe ti ó fi yan ilẹ ibi ti o yàn?

7 Iru awọn eniyan wo ni o n gbé ilu Sodomu?

8 Ilẹ ti Ọlọrun fi fun Abrahamu ti tobi to?

9 Ọkunrin wo ni o yan eyi ti o dara jù?

10 O ha yẹ ki a kọkọ maa lepa nnkan Ọrun tabi nnkan ti ayé?